“Ẹ yẹra fún awọn nkan meje tí n pani run

Lati ọdọ Abu Hurairah, ki Ọlọhun yọnu si i, o gba a wa lati ọdọ Anabi, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, o sọ pe: “Ẹ yẹra fún awọn nkan meje tí n pani run” Wọn sọ pé: Irẹ Ojisẹ Ọlọhun, kí ni awọn nkan naa? Ó ní: “Ṣíṣe ẹbọ pẹlú Ọlọhun, pípidán, pípa eniyan tí Ọlọhun ṣe ní eewọ, àyàfi pẹlu ẹtọ, jíjẹ owó èlé, jíjẹ owó ọmọ òrukàn, sísálọ ní ọjọ ogun ẹsin, ati jíju òkò ṣina mọ awọn obinrin abilékọ, onígbàgbọ ododo, àwọn tí sìná kò sí lórí ọkàn wọn”.

[O ni alaafia] [Ohun ti wọn fi ẹnu kò lé lórí ni]

Ojisẹ Ọlọhun, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a, n pasẹ fún àwọn ijọ rẹ pé kí wọn jinna sí awọn iwa ọdaran ati ẹṣẹ meje ti n pani run, nigba ti wọn wá bi i leere pé kí ni wọn? O ṣalaye pé àwọn ni: Ikinni: Ṣíṣe ẹbọ pẹlu Ọlọhun, nipasẹ wíwá alafiwe ati alafijọ fun Un, èyí ó wù ki o jẹ, mimọ ni fún Ọlọhun, ati ṣiṣe eyikeyii ninu awọn ijọsin fún ẹlomiran tó yatọ si Ọlọhun Allah, Ọba Aleke ọla. Àti pé Ojisẹ Ọlọhun – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – bẹrẹ pẹlu ẹbọ; nitori pe oun ló tobi julọ ninu awọn ẹṣẹ. Ikeji: Idán ṣíṣe – oun naa ni títa kókó àwọn nkankan, ati pípọfọ, ati awọn oogùn, ati awọn èéfín ti n rú jáde – yoo lapa lára ẹni tí wọn bá ṣe idan sí, bii kí o pa ẹni naa, tabi kí ó kó àisàn ba a, tabi kí ó fa ipinya laarin ọkọ ati aya. Isẹ ẹṣù ni, ati pé wọn ò lè rí ọpọlọpọ ninu awọn idan yi ṣe ayafi nipasẹ ẹbọ ati ìpèsè nkan ti awọn ẹmí eṣu buruku nífẹẹ si fun wọn. Ẹkẹta: Pípa ẹmi ti Ọlọhun ṣe ni eewọ lati pa a ayafi pẹlú nǹkan ti o maa sọ ọ di ẹtọ ti o ba ṣẹria mu ti oludajọ ṣẹria sì maa mu u ṣẹ. Ẹkẹrin: Gbígba owo èlé lati lè jẹ ẹ tabi lilo o ní ọna miiran ninu awọn ọna anfaani. Ìkarùn-ún: Ìtayọ àlà sí owó ọmọ kékeré tí bàbá rẹ kú nígbà tí kò ì tîì bàlágà. Ẹkẹfa: Sísá kúrò loju ogun ẹsin pẹlú awọn keferi. Ìkeje: Fífi ẹsùn àgbèrè kan àwọn obìnrin olómìnira, oluṣọra nibi ìranù, àti fífi ẹsùn kan àwọn ọkùnrin bakan naa.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3331